# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,587 THURSDAY DECEMBER 16, 1695 (2D)


## Olori Ẹgbẹ Dẹmo Kan Pada Sinu Ẹgbẹ Afẹnifẹre

ODOGBOLU:— Lati nkan bi oṣu kan sẹhin ni irohin ti nde si ile iṣẹ wa lori ọkcaimọye awọn Ọba, Ijoye, Adajọ, Ijọba ibilẹ Olori ẹgbẹ Dẹmọ, awọn ọmọ Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ati awọn amugbalẹgbẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn nbinu fi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ti nwọn si npada sinu ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA).

Ninu irohin to tun de ile iṣẹ wa ni kutukutu owurọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni a ti gbọ wipe olori ẹgbẹ Dẹmọ ni ilu Odog bolu l'ẹba Ijẹbu Ode Ọgbẹni Adelaja Shotubo ti ngbe ni Ikoso Street Odogbolu binu fi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ti o si pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Naijiria.

Ninu ọrọ Ọgbẹni Adelaja Shotubọ ninu iwe ti o fi binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ni o ti ṣe alaye pe on kuro ninu ẹgbẹ na nitori pe ẹgbẹ Dẹmọ ko fẹ ire ilọsiwaju ati eto alafia mọ awọn enia Ipinle Iwọ Orun Naijiria.

O tun ṣe alaye ninu ipari ọrọ rẹ pe ko si ohun rere kan ti o jade lati ọwọ awọn ẹgbẹ Dẹmọ fun ọdun mẹta ti nwọn fi ṣe eto akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

# NWỌN FẸ PARI IJA LARIN ẸGBẸ DEMỌ ATI UPGA

IBADAN:- Ni ọjọ iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinla osu yi ni awọn Igbimọ kan ti nwọn npe ni Yoruba Elder Peace Committe eyiti Adajọ agba fun orile ede Naij ria Oloye Adetokunbọ Ademọla ṣe olori won ni irohin fi ye wa pe nwọn se eto ipade kan lati pari e.(cai.e(e t) ns lẹ larin ẹgbẹ Dẹmọ ati ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA) ni nwọn si ba awọn olori ẹgbẹ na ṣe ipade lati pari ija to wa nilẹ na.



Ọba Adesọji Aderẹmi Oni Ifẹ

Irohin na tun fi ye wa p awon Igbimọ ẹgbẹ na sa awọn asoju ẹgbẹ (UPGA) eyiti Adele egbe Afẹnifer e Alhaji Dauda Soroye Adegbenro jẹ olori wọn se ipade kan ninu ile Ọba Adesọji Aderẹmi Ọni ti ile ifẹ ni ilu Ibadan lati le ri pe nwon fi opin si ija to wa larin awọn Ọmọ ilẹ Yoruba bayi

Oniwe irohin wa to lọ si ile Ọba Adesọji Aderẹmi Ọni ti Ile-Ife lori eto ipade ti awọn Igbimọ na bo Adele Olori ẹgbẹ Afenifere pelu awon Ọmọ lehin re ninu egbe (UPGA) ṣe ni a gbọ wipe ko si ẹniti nwon ṣọrọ kankan fun ni pa ipade na ati pe bonkele ni won fi ipade na ṣe kosi eniti nwọn gba laye lati wọ inu ile nibiti nwọn ti ṣe ipade na.

Oniwe irohin wa ti o wa ni tosi ibiti nwọn ti ṣe ipade ni o ti ṣe alaye pe awọn enia to wa sibi ipade na ni Ọba Adesọji Aderẹmi Oni ti Ilẹ-Ifẹ, Oloye Adetokunbọ Ademọla, Oloye Kofo Abayọmi, Oloye Aminu Kosọkọ, Alhaji A. W. Elias, Imam Muili ti ilu Ibadan ati Olori awọn Imam ni ilu Ibadan, ati Bisọbu Solomon Odutọla.

Irohin tun fi ye wa labẹlẹ pe Alhaji D. S. Adegbenro ṣe alaye fun Igbimọ ẹgbẹ Yoruba Elders Peace Committee lori onunti awọn ẹgbẹ Ajumọṣepọ (UPGA) ṣe alaye le lori pe awọn ki yio gba gbogbo ohunti o lọdi eyiti ko ba eto Oba mu ti ẹgbẹ Dẹmọ fẹ fi jibiti se.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn Igbimọ na tun ba awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ṣe ira ipade ti nwọn ba Alhaji D. S Adegbenro ṣe nibi kan na eyiti iṣe ile Ọba Adesọji Aderẹmi Oni ti Ile—Ifẹ ni irọlẹ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi.



Dokita M. I. Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakukọ



Alhaji D. S. Adegbenro
Adele Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Bakanna ni irohin tun fi ye wa lati Eko pe awọn Igbimọ kan ti iṣe ti egbe awọn Obinrin eyiti a npe ni "National Concil Of Women Societies" ni a g'ọ wipe nwọn kuro ni ilu Eko lọ si Ibadan lati ba awọn Olori ẹgbẹ UPGA ati Dẹmọ jiroro lori bi nwọn yio ti ṣe pari.

Ninu awọn eniti o wa nibi ipade ti awọn egbe Obinrin na ba awọn Olori egbe (UPGA) ṣe ni Alhaji Dauda Soroye Adegbenro ati Iyawo Olori egbe Afenifere Iyaafin H I D Awolọwọ ati awọn Olori egbe Itesiwaju (UPGA) miran



Ademola Adetokunbọ
Olori Adajọ ilẹ Naijiria


## LAGOS CITY COUNCIL

PERMITS FOR OMNIBUSES ENTERING EBUTE-ERO

Applications are hereby invited from Bus Owners for the issue of 200 permits to bring passengers to Ebute Ero on Lagos Island.

Applications must reach the undersigned on or before mid-day on Friday, 24 December, 1965.

The following conditions must be fulfilled before any permit will be issued :—

1. A vehicle for permit must conform with the definition of "Omnibus" as laid down in Section 46(1) and (2) of the Road Traffic Regulations.
2. Applicants must produce their vehicles to the Chief Traffic Office, Lagos City Council, for inspection before 24th December, 1965.

Buses which pass through the preliminary inspection will thereafter take part in a public ballot out of which 200 will be selected.

Dated this 15th day of December, 1965.

S. J. MAYAKI,
Town Clerk.

City Hall
Catholic Mission Street,
Lagos.
15th December, 1965.

## Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

### A Nfẹ Ọjọ Oja Ninu Irohin Imọlẹ

Olotu, mo ro pe o ti to ọdun kan bayi ti a ti ri ọjọ ọja ilẹ Yoruba ka ninu iwe Irohin Imọlẹ eyiti o jẹ wipe lọsọsẹ ni a ma nmọ asiko awọn ọjọ oja ninu Iwe na, ṣugbọn a ko mọ ohunti o da Olotu pẹlu awọn Alabaṣiṣẹpọ rẹ ti nwọn ko fi ṣe eto nipa awọn ọjọ ọja Ilẹ wa eyiti o jẹ wipe u jẹ ohunti o ṣe pataki pupọ awa onkawe nyin si ma ngbadun pupọ lati ma ri i ka.

Mo ro pe Olotu Irohin Imọlẹ ba le t te lati tete jẹki a ri awọn ọjọ ọja wa ka ninu iwe Irohin Imọlẹ bayi. Eleyi si tun jẹ ohunti o ṣe pataki fun awa ti a jẹ Oniṣowo nipa itọka sọna ti iwe Irohin Imọlẹ ma a nṣe fun wa nipa ọjọ ọja.

Inu awa Oniṣowo yio dun bi Olotu ba le ṣe eto gẹgẹbi a o ti ṣe ma ri ọjọ ọja na ka ninu iwe nyin laipẹ yi. A o si ma reti nyin o nitoripe Ijafara lewu o.

Emi ni
RALIATU ABẸKẸ JIMỌH
IGBOGLIA.

### Ibadan Di Bareke Awon Olopa ?

Olotu dakun gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ oloyinmọmọ ti o nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati kesi awọn Ijọba ibilẹ Ibadan ati Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ki nwọn dakun ki nwọn fi ye denu wahala awọn Ọlọpa yi ti pọ ni apọju larin ilu Ibadan a ko ri imu mi rara

Inu wa yio dun bi awọn Ijọba mejeji yi ba le ran wa lọwọ ki nwọn gba wa lọwọ awọn yi ti nwọn nfi iya jẹ wa ni ainidi a ko gbọdọ lọ ọja Ọlọpa niwaju wa Ọlọpa lẹhin wa eyi ti ga ju

Alejo kan wa ki mi awọn Olopa bi merin ti wole wa bere nibo ni alejo na ti wa kini o ṣe iṣẹ kini o nṣe ati awọn ibere ti ko ba eti mu rara eyiti a ko ri iru re ri lati igbati ati nṣe Ijoba fun arawa

O tilẹ wa buru debi pe bi eni ba fẹ lo si baluwẹ Ọlopa fe le bere n kini oluwa re nlo ṣe n ... iwe nitori-na iwa a... Ọlopa yi ti su wa ...apata

Nibiti won ti nja ti nwọn ndana sun ile ati moto Ọlopa ko po to ti Ibadan bi Ijoba ko ba ṣe iṣẹ e ti Ijoba sile fun awon ti ko ti fi Ọlọpa da eru ba wa aiye ni a ba Ijọba Awolọwọ gbe lasiko iku Alhaji Adelabu ilu ko buru to bayi

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni
E Ọjẹwumi
IBADAN

**WANTED**

Advance Apprentice and Apprentice Printers,

Apply In Person

Irohin Imọlẹ's Office

16, Bamgbose Street,
LAGOS

## Ila Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A n O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọ ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu o'ri erin mẹta yi ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu leitaja kakiri Orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS

AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

## ALEBIOSU BOOKSHOP

13 BAMGBOSE STREET, PHONE (21304) LAGOS

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in Stock, Seasonal Lovely & Interesting Xmas Cheque and Xmas Cards in assorted types as:-

| | |
|---|---|
| 1 To my Darling | 2 To my Sweet Heart |
| 3 ,, my Lover | 4 ,, One I Love most |
| 5 ,, my Boy Friend | 6 ,, Husband |
| 7 ,, my Wife | 8 ,, my Sister |
| 9 ,, Brother | 10 ,, my Friend |

You will be mostly impressed if you come to the abo- named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards.

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANC

BERE FUN OJULOWO ADI ELEGBO

## "Congreve's Iodo Form--Ointment'



Atamataṣe ni egbogi" ADI-ELEGBO" yi j fun itọju gbo gbo oriṣiriṣi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹrigbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin sinu yio jeki oju re ru wa soke, yio si pọn daradara run bakaru ko si mọ werewere ni yio si san patapata. Alafia de si ọ niyen :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Eleru tabi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba r ra o;

Bere egbogi yi ni ṣobu awon :—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street. Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

# ỌBA OYEKAN NLỌ SI IPINLẸ ILA ORUN

EKO:— Alaiyeluwa Ọba Adeyinka Oyekan Keji ti ilu Eko yio kuro ni Eko lọjọ Ẹti ti işe ọjọ kẹtadinlogun oşu yi lo si Ipinlẹ Ila Orun Naijiria lo si ilu kan ti on npe Arondizuogu ni agbegbe Orlu awọn ijoye o nfila funfun diẹ yio ba Alaiyeluwa na rin irinajo rẹ akoko ẹhinti o di Ọba Eko lo si Ipinlẹ na

Ọba Oyekan yio de si Onitsha ni kete ti o ba ti kuro ni Eko eyiti Obi ti Onitsha Oloye Onyejekwe ati Alaga Ijoba Ibilẹ Onitsha Ọgbẹni Udenze yio gba Ọba Adeyinka Oyekan ati awọn ijoye rẹ lalejo ni kete ti nwọn ba ti de ilu Onitsha

Bi o ba di Irọle awon ẹmo ẹgbẹ kan ni Onitsha ti nwo[illegible] ko ara wọ jọ yio tun se ase ranpẹ fun Ọba ati awọn emẹwa rẹ Olori Igberiko fun ilu Onitsha Oloye S O Masi ni yio jẹ alaga ọjọ na

Ni ọjọ ti o tele ti işe ọjọ Abamẹta ni Ọba ati awọn Ijoye rẹ iyo kuro ni Onitsha nwọn yio wa si ilu Akokwa lati ibẹ ni nwọn yio ti şeşẹ de si ilu ti nwon nlọ gan an ti o njẹ Arondizuogu ni ibẹ ni nwọn yio ti bere ayẹyẹ ladi şi ile Dokita K O Mbadiwa ti o pe oruko ile na ni "Afin gbogbo enia" Ọba Oyekan ni yio şi omi kekere kan ti o wa nibẹ eyiti o dabi om ti o wa ni Tinubu lEko ni deede agogo mẹrin-abọ irọlẹ ojo na

Lẹhinti nwọn ba ti pari ayẹyẹ ile na tan ni ojọ Abamẹta ni Ọba Oyekan yio ba Dokita Mbadiwe şe faaji ni irọle ojọ na titi di ojọ Aiku ti işe ọjọ kokan dinlogun oşu yi lẹhinna ni Ọba ati awọn ẹmẹwa yio kuro ni ilu Arondizuogu ni agogo mẹwa abọ ọjọ Aiku na wa si ilu Eko


Dokita K, O, Mbadiwe

## YE IRAWO RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Maşe jẹki ara rẹ gbona lori ohunkohun ju, maşe jẹki gbọnmọgbọnmọ tirẹ pọju, şugbọn ko buru bi o ba şe e ni iwọntunwọnsi.

PISCES (Feb 21 – Mar 20) Maşe nikan joko sile ki aarẹ tabi ki ofutu ma mu ọ, şugbọn ki o jade tọ awọn ọrẹ rẹ lọ ki ẹ si jumọ ma mu faaji ki ẹ si ma daraya.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ire mbẹ fun ọ loni, o si yẹ ki o di ara rẹ ni amure fun rere ọjọ oni, igbadun ati idunnu ni yio jẹ fun awọn iyawo rẹ

TAURUS (April 21 — May 20) Ọna bi ọran ara rẹ ti ngba lọ yi ko yẹ ọ si, nitorima, maşe pọn ara rẹ ju şugbọn ki o gba eyiti Ọlọrun ba mu wa. Ayọ mbọ lẹhin rẹ

GEMINI (May 21—June 21) Ọjọ oni dara lati ma lọ gba imọran nipa awọn ohun ti o jẹ işoro fun ọ Aşiri rẹ ati ọrọ ara rẹ ko ni tu sita fun ẹlomiran ri

CANCER (June 22—July 22) Iwọ yio jẹ igbadun ati faaji larin awọn ọrẹ ati ojulumọ, iwọ yio ri awọn fi ọrọ we ara wọn, şugbọn, ki o rẹ iyẹ igberaga rẹ silẹ.

LEO (July 23 Aug 22) Aarẹ ọkan yio şiji bo ọ nşe ni ki o si mọ bi iwọ yio ti şe şe ọja ko si ni lọ soke, to gẹgẹbi iwọ ti lero mọ

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Bi o ba fi ẹgbọn inu ara rẹ gbe ọrọ yi yẹwo iwọ yio şe nkan ti ko ni gbagbe şugbọn ki o yọ gbogbo eyiti o jẹ işoro inẹ kuro

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Aşiri titun kan yio tun yọ si ọ li ọkan Adupẹ lọdọ Ọlọrun ti ko jẹki o ba awọn ẹgbẹ buruku logba ba awọn ẹlẹgbẹ rẹ şe dehun iwọ yio si ri ilọsiwaju nla

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Edekoyede larin iwọ ati awọn ẹbi rẹ yio jẹki gbogbo nkan leju pọ fun ọ loni wa ọna ti iwọ yio fi yọ ara rẹ ki o ma si şe pọn ara rẹ ju

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Iwọ yio şe faaji pẹlu awọn ọrẹ rẹ loni, iwọ pẹlu wọn yio si jijọ şe ade nun şugbọn maşe jẹki inawo rẹ pọju.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Gẹgẹbi o ti şe faaji larin awọn ọrẹ rẹ to bẹẹni lo yẹ ki o şe itọju ara rẹ silẹ fun iru [illegible] ti o [illegible] mbọ


## EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI

**"CYCLEVEN"**

Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni patak fun Ọkunrin ti o si lagbara lati şe iwosan rẹ patapata.
Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odẹ nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la le ri mẹwa ninu ọgọrun ti o le şe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lero wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni. pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Şugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun niẹ iyonu rẹ o sitnn ma bẹrẹ bakanna, Ọrisirişi Jẹdijẹdi ni o wa ini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ul ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa jije Şuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orişirişi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu olusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba uyo ti o ba şe igbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu omusu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa idi rẹ ko ki o si danwo orişi mẹta nio daju wipe iwo yio bo lowo Jedi patapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Nsiria Bere re ni:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4. Tinubu Square Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone:- 22878 Lagos Nigeria (Oja Ita Faji
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street, Yaba
LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

ATI NI ŞỌBU
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

# OHUNTI IṢE IṢẸ ENIA YIKA GBOGBO AIYE

## Lati Oju Ewe Kini

Bi enia ba ranti gbogbo awon ohunti o sele ni gbogbo asiko yi oluware yio ri daju wipe Ọgbeni Lehin ṣe gudugudu meje nipa ija fun Ominira eyiti o wa nigbana lati le ri w pe awon olowo ati gbogbo awon oloro igbanna le fun awon osisẹ ni ere ise won a ni awon ohunti o to si awon osise la ti gba lehin ti won ba ti ṣe iṣe won pari tan

Lẹhin ti awon enia na ti bo ni oko ẹru tan, a ni nigbati nwon ti gba Ominira tan, ni Ọgbeni Lenin to wa bẹrẹs' maa ṣe awon eto ti o to ati gbogbo awon eto ti o tun yẹ fun awon omo ẹgbẹ Oṣiṣẹ ati awon ti won fi eto ati akoso Ijoba le lowo ki gbogbo won le mo bi awon yio ti ṣe maa ṣe nigbati nwon ba de inu iṣẹ won ati nipa bi nwon ti ṣe maa ṣe eto Ijoba ti ilu yio fi maa lo deede.

Nigbati Ọgbeni Lenin ṣe awon eto na sile tan patapata, ni o tun wa ko gbogbo won sinu iwe kan bi awon enia yio ti ṣe maa ṣe Ijoba na ni ona ti yio dara ti ko ni si ija, ogun tabi otẹ larin gbogbo awọn enia larin ilu, ati ni ọna ti ilosiwaju yio ṣe de fun wọn.

Gbogbo enia ni nwọn nra iwe na eyiti Ọgbẹni Lenin kọ, ti gbogbo won si ni iwe na lọwọ gẹgẹbi akọmọna eyiti o nra nigbana gẹgẹbi akara gbigbona lọja nitoripe gbogbo ohunti awọn enia nifẹ nigbana ni nwọn ori wipe, rere ni ayọrisi rẹ njẹ fun awọn ko si eyiti nwọn ṣe ninu ohun ti o kọ fun won ti o ja jọ wọn lowo ri.

Ọgbẹni Lenin tilẹ tun sọ ninu iwe na bi edeaiyede ṣẹlẹ larin awọn enia ti nwọn ba wa ninu Ile Igbimọ Ijọba bi nwọn ti ṣe le pari edeaiyede na pẹlu itunbi ibinu larin ara wọn ti ija na ko ṣe ni le lọ siwaju ju bi o ti ṣe yẹ lọ.

Bakanna ẹwẹ, ni o si tun sọ ni ẹgbẹ kan ninu iwe na bi edeaiyede ba bẹsilẹ larin awọn ẹgbe Oṣiṣẹ ti nwọn nṣe eto Ijọba bi wọn ti se atojubọ si awọn ohun ti o ṣẹlẹ si arin awọn enia mejeji na titi ti nwọn yio fi pari oro na larin ara won pẹlu itunbi inubi.

---


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYAMIREN** TONIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki jamọnu tilun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ dajufun Agbara ati Ajẹbidan iṣẹ I ra agbalagba Ọkunrin ati Obirin gbogbo

Bi arẹ ara bi nmiọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNA MIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di ẹtun pafapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o g hanjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan ni ugba yio sao pẹlu ioq m adeu brode o iyẹn di baş



NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone:- 22878 Lagos Nigeria, (Ọja Ita Faji


---


# GBANJO!

NOVEMEBER 15th — DCEMBER 30th 1965



Iwe itumo Ala,
Etutu Sise ise wiwo,
Ojo ibi Omo, ati
Ogun Ajebidan
3s 6d di 1s 6d

Iwe Afose Isedale
Yoruba ati Psalmu
Ajebidan.
3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Pakẹti di 1/-

o le ri iwe wonyi ra lọdọ :-

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin.

SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,587 THURSDAY DECEMBER 16, 1965 (2D)


## Ijamba Şe Ole Oni'le Kaa Mo

EKO:- Ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni adajọ ile ẹjọ kekere ti ilu Eko pase pe ki ọdọmọkunrin kan Olu Kayọde Famokun yara lọ fi ẹwọn osu mefa jura lori ẹsun ole jija eyiti Ọlọpa to mu wa si ile ẹjọ na ka si lẹsẹ ati pe ọdaran Ọmọdekunrin na si gba wipe on jẹbi ẹsun ti wọn ka si oni lẹsẹ.

Ninu ọrọ Ọlọpa to ba ọdaran Ọmọkunrin na şe ẹjọ ni o ti şe ala ye fun ile ẹjọ kekere pe ni ọjọ ọjọ Bọ ti ise ọjọ kẹsan osu yi ni Olu Kayọde Fanimokun lọ ji ohun Ipa ra kan ni ile itaja awọn Oyinbo onisowo ti a npe ni "Leventis Stores" eyiti iye owo rẹ jẹ pọun meji abẹ (£2 10/-)

Ninu ọrọ Adajọ ile ẹjọ kekere na ni o ti se alaye pe gbogbo ẹsun ti Ọlọpa to ba ọdaran na nse ẹjọ ka si lẹsẹ ni on gba gbọ ati pe ki Ọdaran na yara lọ fi ẹwọn osu mẹfa jura nitori pe o jẹbi ẹsun na

Ninu ọrọ ọdaran na ni o ti rọ ile ẹjọ lati ni oju anu rẹ si on ati pe ki o dariji on nitoripe eşu lo ran on, ko ni şe bẹ mọ

# NWỌN DANA SUN ỌBA KAN LAAYE !

IJẸBU-IGBO:- Jẹbẹtẹ gbe ọmọ le awọn enia to wa ninu ilu Ijẹbu Atan lẹba Ijẹbu Igbo lọwọ nigbati awon enia kan dana sun ọba Okunşelu ti Itan Ijẹbu ti o tun jẹ ọkan ninu ọmọ Ile Igbimọ Lọba lọba titun ti nwọn şẹşẹ yan laipe nigbati oloye Keleko nbọ lati Ibadan nibiti o ti lọ fun ipade awọn ọba ati Ijoye eyiti nwọn şe ni ọjọ ọjọ Bọ ti işe ojọ kẹsan oşu yi.

Irohin fi ye wa pe awọn enia na ti duro si ibudo awọn onimọto ti ilu na lati duro de Balẹ na nigbati o nbọ lati Ibadan nibiti o ti lọ fun ipade awọn lọbalọba eyiti o jẹ wipe gẹgẹbi ọba na ti sọkalẹ lati inu mọto ni awọn enia na ti da epo mọto si lara ti nwọn si dana si pẹlu.

Irohin tun fi ye wa pe lẹsẹkẹsẹ ti nwọn ti dana ni oba tete yara sare lọ sinu Igbo kan lati le pa ina na, Şugbọn ki awọn enia to de ibẹ lati lọ şe Iranlowọ fun ni gbogbo ara ọba ni ti jo raurau eyiti o jẹ wipe ọba na si ku.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe nigbati awọn enia na de ibiti ọba na sa lọ ninu Igbo na ni nwọn ba gbe e lọ si ile Iwosan ti awọn Aguda ni ilu Agọ-Iwoye lati lọ şe itọju rẹ şugbọn ninu ile Iwosan na lo ku si.

Awọn Ọlọpa si ti de ilu Atan bayi lati lo ma şẹ iwa di awọn enia to dana sun Ọba ilu na. A gbọ wipe ko si ẹnikẹni ti awọn Ọlọpa ti mu lori ohunti o şẹle si ọba na.

Ninu Irohin ti o tun de ile işẹ wa lati Shagamu ni a ti gbọ wipe awọn enia kan tun dana sun ile olori ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) Ọgbeni Amudu Lawal eyiti o jẹ wi pe gbogbo inu ile na lo jona patapata ni owurọ ọjọ Aiku ti işe ọjọ kejila osu yi

Irohin na tun fi ye wa pe awọn enia na si yi ile Ọgbeni Amudu Lawal ka eyiti o jẹ wipe awọn si da epo moto yi ara ile na ka ki nwọn to dana sun ile na.

Oniwe irohin ilu Shagamu tun fi ye wa pe awọn ẹbi ati ọrẹ Ọgbẹni Lawal ti ko gbogbo ẹru wọn kuro ninu ile na a ti pe ọsẹ kan şẹhin ni irohin ti nde owo won pe awọn enia kan yio dana sun ile wọn

Bakanna ni irohin rogbodiyan nla kan tun bẹ silẹ ni ilu Ipẹru larin awọn ọmọ ẹgbẹ oselu eyiti o je wipe opolopo enia ni nwọn ti gbe lọ si ile iwosan ti ilu Shagamu lati lo şe itoju won lori Ọgbẹ ti nwon fi ara gba ninu rogbodiyan to şẹlẹ ni ilu na ni opin osẹ to koja lo yi.

Ninu awọn enia to fi ara gbọgbẹ ti nwọn si gbe lọ si ile Iwosan ti ilu Shagamu lati lọ şe itọju wọn ni Oloye Lisa ti ilu Ipẹru ti o jẹ igbakeji ọba Alaperu ti ilu Ipẹru ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ. Irohin fi ye wa pe ni ẹsẹ ni Oloye Adeyẹmi ti fi ara gbọgbẹ eyiti nwon fi tete gbe lọ si ile Iwosan na fun itọju.

Ni ilu Ode-Lemọ lẹba Shagamu ni awọn enia kan ti lọ kolu ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ ilu na eyiti o jẹ wipe gbogbo ile ẹjọ na lo si jona patapata bakanna ni awọn enia na tun lọ dana sun ile ti Ijọba ibilẹ na kọ si ibuda ọkọ ti ilu na eyiti o fi jẹ wipe gbogbo ile na lo si jona patapata.

Şugbọn awon olopa lo ti ri ẹnikankan mu ninu awọn enia to dana sun awọn ile mejeji na ti ilẹ na. Şugbọn a gbọ wipe awon olopa ti nşe iwadi awon enia ti o dana sun ile ẹjọ ti Ijọba ibilẹ na ati ile işẹ ibiti nwọn ti ngba owo lowo awon onimoto ni ibudo oko ti ilu na.

# Adajọ Binu fi ipo Rẹ silẹ

IKẸNNẸ: Ni ojo ọjo Ru ti Işe ojo kẹdogun oşu yi ni irohin de ile lẹ wa pe Adajọ kotu ti Ijọba Ibilẹ ti ilu Ikenne ti o tun jẹ Ọba ti Idotun ni ẹkun Ijẹbu—Rẹmọ oloye Sobọla Opeaiye ni a gbọ wipe o binu fi aye rẹ silẹ gẹgẹbi Adajọ kotu ti Ijoba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ.

Irohin tun fi ye wa pe oloye Sobola Opeaiye to tun binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmo (NNDP) o si ti ko iwe lati di omo ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti oloye Opeaiye tun şe alaye pe on si jẹ okan patapi ninu ẹgbe Afẹnifẹre eyiti oloye na tun pada si bayi

Ninu iwe ti oloye Sobola Opeaiye fi kuro ninu ẹgbẹ Dẹmo ti o si pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti oloye Opeaiye fi ranşẹ si Akowe ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilu Ikẹnnẹ eyiti o tun fi ẹda iwe na ranşẹ si Ibadan ni oba na ti şe alaye pe on binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmo ati pẹ on ni ireti pe nwon yio si gba on pada sinu ẹgbẹ Afenifere eyiti on ti jẹ omo egbe na tele.

Ninu oro Oloye Opeaiye ni o ti şe alaye pe on ko fi igba kan gba iwe ẹgbẹ Dẹmo lọwọ tabi pe ki on fi oruko silẹ gẹgẹbi omo ẹgbẹ na bikoşe pe bi nwọn fi yan on gẹgẹbi Adajo kotu ti Ijoba ibilẹ onipo kẹta,

Ninu iwe ti Oloye Sobola fi ipo rẹ silẹ gẹgẹbi Adajo kotu ti Ijoba ibilẹ ti ilu Ikenne eyi ti o ko si Alakoso Igbimọ eto Ijọba Ibilẹ ti Ipinlẹ Iwọ Oru Na'jiria ni Oloye Sobola ti şe alaye ninu iwe na pe ki nwon tete şe eto ti o to ti o yẹ lati yọ oruko on kuro gẹgẹbi Adajo kotu ti Ijoba ibilẹ ti ilu Ikẹnnẹ ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ,


Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 16/12/65